# ODO OMI IYE

## Ifihan 22:1-21

## ẸKỌ 467 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi ìye na lọfẹ" (Ifihan 22:17).**

### Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun

Awa ti o gba anfaani awọn iriri ti Ọlọrun ni lati fun ni, eyi ti i ṣe ti igbala, isọdimimọ ati ifi Ẹmi Mimọ wọni, ti a si n gbé igbesi-ayé wa fun Jesu lojoojumọ, nigbooṣe, lai pẹ a o ri ayé yii ti yoo dara lọpọlọpọ ju bi o ti wà lonii yii lọ. Gbogbo awọn nnkan ti n hù -- awọn igi, itanna, ewebẹ -- yoo lẹwa, yoo tobi, yoo si dara ju bi wọn ti wà ri lọ. Gbogbo awọn ẹranko, ati ejo paapaa, awọn kiniun ati amọtẹkùn ni a o ti tù loju, awa ki yoo si bẹru nitori Jesu yoo jẹ Ọba fun ẹgbẹrun (1,000) ọdun.

### Ọrun Titun ati Ayé Titun

Ọpọ nnkan ni o wà sibẹ lati fojusọna fun, eyi ni igba ti Ọlọrun ba dá Ọrun titun ati ayé titun. Ninu ayé titun yii ni awọn eniyan titun yoo wà, awọn eniyan ti a sọ di titun nipa gbigba wọn là ninu ayé nihin. "Nitorina bi ẹnikẹni ba wà ninu Kristi, o di ẹda titun: ohun atijọ ti kọja lọ; kiyesi i, nwọn si di titun" (2 Kọrinti 5:17). Ọlọrun yoo rán ilu kan ti a n pè ni Jerusalẹmu Titun sọkalẹ lati Ọrun wá. Odo Omi Iye yoo maa ṣàn la igboro Ilu yii kọja.

### Igi Iyè

Igi ti o hù ni iha mejeeji Odo Omi Iyè naa ni Igi Iyè. Ki i ṣe iru eso kan ṣoṣo ni igi yii ni, ṣugbọn o n so oriṣi eso mejila. Ni oṣooṣu ni igi naa yoo maa rudi, ti yoo maa tanna, ti eso rẹ yoo si maa dagba lori Igi Iyè. Awọn orilẹ-ède, ọpọlọpọ eniyan ti n gbé inu ayé titun, yoo wọle, wọn yoo si tun jade lati inu awọn ẹnubode Jerusalẹmu Titun, nitori nigba gbogbo ni awọn ẹnubode wọnyii ṣi silẹ. Kò si oru nibẹ. Awọn eniyan yoo jẹ eso Igi Iyè, wọn yoo si yè titi lae.

Ọlọrun ti pese Igi Iyè yii fun Adamu ati Efa ni ipilẹṣẹ ọjọ iwà. Wọn i ba ti jẹ ninu rẹ ki wọn si yè titi lae nigba naa, ṣugbọn dipo eyi, wọn ṣe aigbọran a si le wọn jade kuro ninu Ọgba naa. Lati ọpọlọpọ ọgọrun ọdun wọnyii wá, lati akoko Adamu ati Efa titi dé akoko didá ayé titun, eniyan kò ni ẹtọ si Igi Iyè. Nisisiyii, Igi Iyè tun wa ni Jerusalẹmu Titun, gbogbo awọn orilẹ-ede ayé mu ninu ewe rẹ, nigbakuugba ni ara wọn da ti wọn si lagbara. Wọn yoo jẹ eso Igi naa, wọn ki yoo si kú mọ.

Eṣu ko ni le wá si ayé titun yii, nitori a dè é ni ọrun-apaadi titi lae pẹlu gbogbo awọn eniyan ti o kọ lati ronupiwada iwa buburu wọn ninu ayé isisiyii. Awọn ti ẹru n bà lati tẹle Kristi nitori ohun ti awọn eniyan yoo wí tabi ti wọn yoo ṣe, ati awọn ti wọn n purọ, paapaa "irọ funfun" kékèké ati awọn wọnni ti wọn ṣe ohun buburu gan an, ni a dè ni ọrun-apaadi pẹlu eṣu. Wọn kò le jade. Eefin oró wọn goke lọ lae ati laelae.

### Jerusalẹmu Titun

Ẹ jẹ ki a fi ọkàn rò pe a wà ni Jerusalẹmu Titun nisisiyii. A kò ni tan iná lati fi imọlẹ si oju ọna wa, bẹẹ ni a kò ṣẹṣẹ ni duro titi oorun yoo fi ràn, nitori Ọlọrun tikara Rẹ ni imọlẹ Ilu naa. Olukuluku ti o wà ni Ilu naa ni orukọ Oluwa ni iwaju rẹ. Bi a ti n ṣe akiyesi, a n ri wọn bi wọn ti n lọ sihin sọhun ti wọn n jiṣẹ fun Ọlọrun ati fun Jesu. Wọn rán wa leti awọn iranṣẹ awọn Ju ni akoko Mose. Lẹyin ọdun mẹfa ti wọn ti n sin oluwa wọn, wọn di ominira lati fi oluwa wọn silẹ, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba wí ni gbangba pe oun fẹran oluwa oun ati pe oun fẹ duro lọdọ rẹ yoo duro ti òpo ẹnu-ọna, oluwa rẹ yoo si lu ihò si isalẹ eti rẹ. Titi lẹyin eyi yoo maa gbé ami yii ti o fi hàn kaakiri pe o fẹ sin oluwa rẹ titi lae (Ẹksodu 21:5, 6).

Lonii, Onigbagbọ ni ominira lati lọ kuro lọdọ Ọlọrun ki o si maa sin eṣu, ṣugbọn o n fi hàn gbangba pe oun fẹran Ọlọrun, oun si fẹ sin In titi lae. O ni ami iranṣẹ Ọlọrun. Ki i ṣe ami ti a fi oju ri ni eti tabi iwaju, ṣugbọn awọn nnkan ti o n sọ, awọn nnkan ti o n ṣe ati awọn ibi ti o n lọ n fi hàn pe ọmọlẹyin Jesu ni oun i ṣe.

Ninu ifọkanro wa, a ri awọn wọnni ti wọn ti sin Ọlọrun ni ayé, nisisiyii wọn n rin ni ita wura didán, nigba gbogbo ni wọn wà ni iwaju Ọlọrun ti wọn ti yàn lati sin titi lae. Ohun kin-in-ni ni pe, wọn yàn lati sin Ọlọrun nigba ti wọn wà ni ayé nihin; wọn sin Ọlọrun ni akoko ẹgbẹrun ọdun alaafia; nisisiyii ninu Ọrun Titun ati ayé titun, sibẹ wọn n ṣe awọn nnkan naa gan an ti o mú ayọ nlá nlà bá ọkàn wọn.

**N Bọ̀ Kánkán**

Ni ẹsẹ kẹfa, angẹli ti o ti fi awọn nnkan pupọ wọnyii han Johannu sọ pe Ọlọrun ti rán oun lati fi awọn ohun ti ko le ṣai ṣẹ kankan hàn. Eyi nì ni pe awọn ohun ti yoo ṣẹlẹ ninu ayé wa isisiyii ninu eyi ti a n gbé, ati awọn ohun wọnni ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju pẹlu. Fun iwọ ti o n ka awọn ọrọ wọnyii, Jesu n wi pe “Kiyesi i, emi mbọ̀ kánkán: ibukún ni fun ẹni ti npa ọrọ isọtẹlẹ inu iwe yi mọ́.” Ipadabọ Jesu yoo jẹ iyanu fun ọpọlọpọ awọn eniyan ti wọn n gbé ninu ayé isisiyii, ṣugbọn bibọ̀ Rẹ̀ kò yẹ ki o ba ọ lai rò tẹlẹ nitori iwọ ti ka gbogbo Iwe Ifihan, iwọ si mọ̀ pe Jesu le dé ni igbakigba. Bi o ba n gbọran ti o si n gba gbogbo ohun ti o mọ̀ nipa Ọrọ Ọlọrun, iwọ yoo jẹ́ ọ̀kan ninu awọn alabukun-fun wọnni ti a gbà soke nigba ti Jesu ba de.

**Ere Naa**

“Igba kù si dẹ̀dẹ.” ni Iwe naa wi. Akoko bibọ Jesu sun mọ tosi, nigba ti ipe ba si dun, ko ni si akoko lati gba awọn ẹlẹṣẹ là tabi lati sọ awọn ti a ti gbala di mimọ́ (ẹsẹ kọkanla). Jesu yoo wá lojiji, yoo si fi ere fun awọn ti wọn ti fi otitọ ọkàn tẹle E, ni fifun wọn ni àye lẹgbẹ Rẹ̀ ni Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, lẹyin naa ni yoo fun wọn ni ipo ninu Ijọba Rẹ̀ ti ẹgbẹrun ọdun alaafia, ati anfaani lati gba awọn ẹnubode Jerusalẹmu Titun wọle, ati lati ni ẹtọ si Igi Iye naa.

Jesu ti pese gbogbo nnkan wọnyii paapaa fun awọn eniyan ti wọn fẹran Rẹ̀ ti wọn si sin In (Johannu 14:1-3). Ṣugbọn ẹlẹṣẹ, nibo ni yoo wà? Kò ni ẹtọ si Igi Iye; yoo wà ni ọrun-apaadi titi lae, ibi oró ti n fi iná ati sulfuru jó. Yoo maa ká eso ere iṣẹ buburu oun tikara rẹ̀.

**Wá**

Jesu rán angẹli naa lati sọ fun Johannu lati kọ Iwe Ifihan ki a ba le mọ ohun ti n bọ̀ wa ṣẹ, ki a si le mura silẹ. Njẹ nisisiyii, bi akoko ti n suré tete, ti Jesu si fẹrẹ de ná, gbogbo Ijọba Ọlọrun ni o para pọ̀ lati pe gbogbo eniyan lati wá gba ninu Omi Iye, ki a si gba wọn là. “Ati Ẹmi ati Iyawo wipe, Mã bọ̀. Ati ẹniti o ngbọ́ ki o wipe, Mã bọ. Ati ẹniti ongbẹ ngbẹ ki o wá. Ẹnikẹni ti o ba si fẹ, ki o gbà omi ìye na lọfẹ.”

“Nitõtọ emi mbọ̀ kánkán,” ni Jesu wi. Njẹ ọkàn rẹ dahun pe, “Mã bọ, Jesu Oluwa”?

**AWỌN IBEERE**

1 Ki ni Omi Iye?
2 Nibo ni a ti kọ́ darukọ Igi Iye?
3 Iru awọn eniyan wo ni o lẹtọọ si Igi Iye?
4 Ki ni ami ti awọn ọmọ-ẹyin Jesu ní nisisiyii?
5 Ki ni ọ̀kan ninu awọn ohun wọnni ti kò le ṣai ṣẹ kánkán?
6 Njẹ àye yoo wà lati ri igbala nigba ti Jesu ba dé?
7 Ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn wọnni ti o lẹtọọ si Igi Iye?
8 Nibo ni awọn ẹlẹṣẹ yoo wà?
9 Ipe wo ni o n jade nisisiyii nipasẹ Ẹmi Ọlọrun ati gbogbo awọn eniyan Ọlọrun?
10 Nigba ti Jesu wi pe, “Nitõtọ emi mbọ̀ kánkán,” ki ni idahun rẹ?